*Ireti Eda…!*

**EPISODE 16**

**<u>Characters</u>**

*Abokede*
*Bello*
*Lukman*
*Baba Wasiu*
*Ashake*
*Ajani*

---

**Scene 1**
**Ilorin. Abokede's work-place. Afternoon.**

1. **SFX**: **<u>CAR DRIVES OFF MIC AND GRADUALLY COMES ON MIC CAR STOPS. DOOR OPENS AND CLOSES</u>**
2. **BELLO**: Abokede ba wo ni.
3. **ABOKEDE**: Bello, (**SHYLY**) Ki le n se nibi niru asiko yii?
4. **BELLO**: (**CHUCKLES**) Asiko ounje osan niyii, mo wa ni ki n war a recharge card nibi .
5. **ABOKEDE**: E maa pe gan ni o, gbogbo igba le ma n ra recharge card.
6. **BELLO**: (**LAUGHS**) Mo ro pe eyi maaje ki inu re dun.
7. **ABOKEDE**: (**CHUCKLES SHYLY**) Bee ni o. I nu mi ma n dun ti mo ba ti n taja mi ni gbogbo igba.
8. **BELLO**: Bee ni, ni gbogbo igba.
9. **ABOKEDE**: E gba.
10. **BELLO**: O seun, owo re ree.
11. **ABOKEDE**: E seun.
12. **BELLO**: (**CAREFULLY**) Em.. Abokede, Mummy si fe ri e o
13. **ABOKEDE**: (**SHOCKED**) Kilode, se o si?
14. **BELLO**: (**LAUGHS**) Ma beru, won kan fe ri e, ki won si dupe lowo re ni .
15. **ABOKEDE**: (**NERVOUSLY**) Kin ni mo se ti won fe kimi. E wo e dakun, e ma so nnkan ti mo se di nnkan babara kan o.
16. **BELLO**: O daa biwo o bam on, nnkan babara lo se. Paapa fun emi.
17. **ABOKEDE**: Hen se bi o si ti dupe lowo mi iyen naa ti to. N o fe tun lo ri awon family kankan mo o.
18. **BELLO**: Kini idi abajo o?
19. **ABOKEDE**: E woo, emi o mo o.

20. **BELLO**: Woo Abokede, emi ni ko see lati ojo ti mo ti so fun won pe iwo lo bami gbe bag yen wa ni Mummy ti n so pea won fe mo e. Mummy si ni atenumo gan-an ni. Joo eekan na ni waa wa.
21. **ABOKEDE**: ko sogbon ti mo fi le wa se, iwo naa rii bi mo ti busy to.
22. **BELLO**: O le wa ti o ba close.
23. **ABOKEDE**: Ko seese, mo ma tete lo sile lo ran Aunty mi lowo.
24. **BELLO**: Weekend nko nigba yen?
25. **ABOKEDE**: Mo ma n lo si JAMB lessons ni gbogbo opin ose.
26. **BELLO**: Abokede o si jo ko dawon lohun. Won ti n sareri re, yoju si won lekan!
27. **ABOKEDE**: (**RELUCTANTLY**) Odaa mo ti gbo
28. **BELLO:** **(ELATED)** O seun, abi waa kuku wa lale yii,ko so address ile yin fun mi ki n wag be e lale yii.
29. **ABOKEDE:** ki lo le to bee, se bi mo mo ile yin, maa wa fun ra mi. E saa fun mi lasiko die.
30. **BELLO:** Aago mejo lale oni?
31. **ABOKEDE:** Ko si wahala, maa wa.
32. **MUSIC:** **BRIDGE MUSIC UP AND FADES TO**

**Scene 2**

**Ibadan! Lukman's residence. Evening**

33. **SFX:** **SOUND OF LIP SMACKING AND FINGER LICKING, FOLLOWED WITH SIGHS OF ENJOYMENT AND SATISFACTION**
34. **BABA WASIU**: Lukman ore mi, mo gbadun Ounje yii po.
35. **LUKMAN**: (**CHEWING**, **MOUTHFUL**) Hmm, emi naa gbadun re.
36. **BABA WASIU**: (**SIGHS WITH SATISFACTION**) Beeyan ba je iru Ounje bayii tan, beer to ba tutu daadaa lo ye keeyan mu lee.
37. **LUKMAN**: (**CHUCKLES**) Kii se ninu ile mi loti mu Oti.
38. **BABA WASIU**: (**LAUGHS**) Ore mi, ebi mi ko……………….ta lo se Obey ii,owo yii jo owoo Abokede.
39. **LUKMAN**: Abokede ke? Abokede wa n'ilorin. Awon kan t'omo won n se Wosilat ni won gbounje ranse lati Mosalasi.
40. **BABA WASIU**: Ha mo ti gba gba, se o sa n se daadaa n'ilorin
41. **LUKMAN**: (**PROUDLY**) O n se daadaa gan ni. Koda o ti rise bakan naa lo si n gbaradi fun idanwo JAMB re.
42. **BABA WASIU**: O da bahun bi Abokede ti wa n'ilorin . Mo si mo pe yo se daadaa lohun. (**SINGING**) Abokede, omo Shakira, omo re bii iyan

(Abokede, Shakirat's daughter, a child as good as the pounded yam)

43. **LUKMAN**: Sugbon mo mo lilo re lara o.

44. **BABA WASIU**: Iwo nikan ko lo mo on lara, emi naa mo on lara. Abi ojo wo ni mo ti jehun gidi bayii nile re?

45. **LUKMAN**: (**LAUGHS**) Oh, tori ounje ni kan niwo fi mo on lara?

46. **BABA WASIU**: (**UNABASHEDLY**) Ninu gbogbo nnkan ni mo ti mo on lara o. Koda ile yii gan mo pe Abokede o si ninu ohun. Se bile re ti ma n ri tele niyii?

47. **LUKMAN**: (**MILDLY DEFENSIVE**) Ise ile yii ti poju, Iyabo nikan o le daa se.

48. **BABA WASIU**: Awon omo re nko? Aburo re alariya ojojumo nko?........em em Tayo.

49. **LUKMAN**: Ise Tayo ati ile iwe awon omo ni o je won o raye. Ise yen ti wa poju fun Iyabo nikan.

50. **BABA WASIU**: Sugbon nigba ti Abokede wa nihin, oun nikan ni daya ko gbogbo re. O tie daa bayii, gbogbo yin le ma moyi re.

51. **LUKMAN**: (**SIGHS**) Odo Wosilat lo wa bayii.

52. **BABA WASIU**: kin ni won wa so fun o nipa iwa re lohun?

53. **LUKMAN**: (**BEAMING**) Wosilat n soro re daadaa ni o. O ni omo daadaa ni Abokede.

54. **BABA WASIU**: Ko seni ti Abokede le gbe lodo re ti o ni gbadun re, Omo daadaa ni Abokede.

55. **LUKMAN**: Bee ni omo daadaa ni o . (**SADLY**) O kan n mu mi ranti Iya re ni, Sikirat.

56. **BABA WASIU**: Olohun o kuku bawa tee safefe re. (**HE BEGINS TO SING LUKMAN'S PRAISE SONG IN AN ATTEMPT TO LIVEN UP HIS MOOD**)

57. **LUKMAN**: (**LAUGHS**) O seun Baba Wasiu.

58. **MUSIC:** **BRIDGE MUSIC UP AND FADES TO**

**Scene 3**

**Ilorin! Ajani's residence. Early morning!**

59. **SFX**: **<u>COCK CROWS</u>**

60. **SFX:** **<u>SHOES CLICKING THE FLOOR AS ASHAKE WALKS DOWN THE CORRIDOR. SUDDENLY SHE HITS HER FEET ON SOMETHING AND HER BAG FALLS TO THE GROUND</u>**

61. **ASHAKE**: (**GASPS AS SHE ALMOST FELL, EXCLAIMS**) Ta ni o?

62. **AJANI**: (**A LITTLE DISORIENTED**) Yee? (**VERY APOLOGETIC**) Oh, pele Ashake pele.

63. **ASHAKE**: (**A LITTLE UPSET**) Emi ni Boda Ajani, e gbemi subu tan, e wo bag mi ati gbogbo nnkan ti mo ko dani nile. Ki le sun nita tan laaro kutukutu.

64. **AJANI**: (**PACKING HER THINGS FROM THE FLOOR**) Dakun ma binu Ashake, n o gburo ese re pe o n bo. Gba bag re.

65. **ASHAKE**: (**PAUSE, THEN WITH CONCERN**) Boda Ajani kilode? Se ko si wahala Kankan. Se ibi le sun moju ni?

66. **AJANI**: Ko si wahala Kankan ma je ji n da e duro tete maa lo sibi ise re.

67. **ASHAKE**: (**SOMEWHAT AGGRESSIVELY**) Ha haa, e le so fun mi pe ko si nnkan. E sun nita moju e so pe ko si nnkankan. Se eyin ati Iyawo yin n ja ni?

68. **AJANI**: (**QUICKLY**) Ija ke? Ko sija.

69. **ASHAKE**: Ki wa lo sele, e so fun mi.

70. **AJANI**: Wosilat ni, asiko mokan re lo wa.

71. **ASHAKE**: Nigba naa wa n ko?

72. **AJANI**: (**GRUMBLING**) So mo pe ti mo ba lo sun pelu re, mo le lo ta luu, so si mo pe elede eeyan ni. Olohun see, a si fe loyun bayii.

73. **ASHAKE**: (**CHUCKLES UNBELIEVINGLY**) Se nnkan ti e n so ye mi sa? Tori pe Iyawo yin wa ni OVULATION period le fi sun ile pelu Iyawo yin. Ki e ma ba seesi lasepo, ko ma wa lo d'oyun? Tori e le fi sun inu yara, le wa fin sun nita.

74. **AJANI**: Hmm mm

75. **ASHAKE**: (**BURSTS OUT LAUGHING, CLAPPING HER HANDS**) E gba mi o. **(LAUGHING) Boda mi, n o le gba nnkan ti en so yii gbo. Se nnkan ti e n so nipe gbogbo igba ti o ba ti je ovulation period iyawo yi e ni sun mo on, abi? E le so fun mi pe e gbo nipa CONDOM ri laye yin o.**

76. **AJANI**: Ki lo n so ti o dun yii, se ma wa ma lo condom pelu Iyawo mi ni. Nigba ti kii se pelu Obinrin mi nita

77. **ASHAKE**: (**SERIOUSLY**) Ta lo so fun yin pe eewo ni lati lo condom pelu Iyawo yin? Bi e ba lo condom awon ona po lorisirisi ti e le lo ti e si maa sun t'iyawo yin, ti ko si ni loyun.

78. **AJANI**: (**EXCITEDLY**) Ashake, se looto?

79. **ASHAKE**: Se oro ti mo n ba yin so jo awada loju yin? Eyin mejeeji e lo si ago eto ilera to ba wa ni toosi ki e lo se ifeto-somo-bibi. E wa ibi ti ami idanimo b wa to ni awo b lue, yellow ati orange ti won ko

GET IT TOGETHER si. E lo sibi won bayin soro won a si fun yin nimoran lori eyi ti yoo baayin lara mu.

80. **AJANI**: Ti mo si ti n fiya jera milati ojo yii wa. Ashake ti n to n so yii ba fi ri bee. Ah, Wossy mi ogbadun mi to.

81. **ASHAKE**: (**LAUGHS**) Ko si wahala, o ma ri bee ti fe.

82. **AJANI:** **(UNSURE)** Bawo lo ti daa o loju to bayii, Ashake?

83. **ASHAKE:** Eyin naa mo Boda Ajani pe n o gboyun esin wa sile ri lati ojo ti e ti mo mi. Eh-hen (**PAUSES AND TEASING**) O ga fun yin sa, se pe e o le mara duro fun Iyawo yin..

84. **AJANI**: Maraduro fun Wosilat, n o le see.

85. **MUSIC:** **BRIDGE MUSIC UP AND FADES TO**

**Scene 4**

**Ilorin! Abokede's work-place. Afternoon!**

86. **SFX**: <u>**CAR GRADUALLY DRIVES COMING ON MIC! CAR STOPS. DOOR OPENS AND CLOSES SHARPLY SLIGHTLY OFF MIC**</u>

87. **ABOKEDE**: (**ON MIC, HAPPY)** Bello!

88. **BELLO**: (**COMING ON MIC, TIGHTLY**) Ki lo n pa o lerin Abokede?

89. **ABOKEDE**: **(ON. SOBER)** Mo ri loju yin pe o n binu….**(STALLS)**

90. **BELLO**: **(ON)** He ehn, kilode to wa? Abokede, ti o wa da gbogbo family mi duro lori asan.

91. **ABOKEDE**: (**SURPRISED**) Se looto, e ma binu mi o mo….

92. **BELLO**: O so pe o n bo, Abokede. Mummy ni lati lo se wahala ati dana fun e, o si wa.

93. **ABOKEDE**: (**SHOCKED**) Mo dagun, ha. (**APOLOGETICALLY**) Ah Mr Bello, e ma binu.

94. **BELLO**: O ti so idi abajo ti ko je ko wa fun mi.

95. **ABOKEDE**: Mi o mo bi maa ti wa, oju a kan maa timi ni.

96. **BELLO**: Sugbon o kan deede wa emi ni mo mo pe e. O si so fun mi pe waa wa.

97. **ABOKEDE**: Mo kan gba lati wa nigba ti iyolenu yin po lojo yen ni. Ki e fi le fimi lorun sile.

98. **BELLO**: Se pe o puro fun mi lojo yen ni. Ki lo n seleri nnkan ti o ni lese si?

99. **ABOKEDE**: (**VERY APOLOGETIC**) E dakun, e ma binu Mr Bello, e fori jin mi. Oju n timi lati wa sile yin ni. (**ALMOST IN TEARS**) mi o mo pe wiwa mi se Pataki bee. E maa binu …

100. **BELLO**: Mo ti gbo, o kan je pe gbogbo eniyan lo dun pe o wa. Paapaa Mummy mi.

101. **ABOKEDE**: E dakun e bami be won. E je ki won mo pe n kii somo bee.

102. **BELLO**: Emi ko ni maa bee bewon. Iwo ni waa wa funra ara re lati wa bewon...

103. **MUSIC: BRIDGE MUSIC UP AND FADES TO**